# ÌBÍ MOSE -- IGBA ÈWE RẸ̀ NI ILẸ̀ EGIPTI

## Ẹksodu 2:1-25

## ẸKỌ 46 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: “Nipa igbagbọ́ ni awọn obi Mose pa a mọ́ fun oṣu mẹta nigbati a bi i” (Heberu 11:23).**

### Awọn Ayanfẹ Ọlọrun

Ọdun pupọ ti kọja lẹyin iku Josẹfu. Farao ti o ti jẹ oninuure si awọn Ọmọ Israẹli ti kú pẹlu, ọba titun ti o jẹ si ti gbagbe pe ọ̀kan ninu awọn Ju wọnyi ni o gba ara Egipti silẹ ni akoko ìyan. A le ro pe wọn yara gbagbe, ṣugbọn bi a ba boju wo ẹyin wo akoko Ogun Ayipada ti kò ti to igba ọdun, a o ṣe akiyesi pe a kò naani ohun ti o ṣẹlẹ nigba naa.

A ranti pe nigba ti ẹbi Jakọbu lọ si Egipti wọn jẹ àádọrin eniyan (mẹrin-din-laadọrin lati Kenaani wá, Josẹfu, aya rẹ ati awọn ọmọ rẹ mejeeji, gbogbo wọn jẹ aadọrin); ṣugbọn laarin ọpọlọpọ ọgọrun ọdun ti wọn gbé nibẹ, awọn eniyan wọnyi ti pọ̀ pupọ to bẹẹ ti ọba Egipti fi bẹru pe wọn yoo lagbara ju awọn ara Egipti lọ, wọn yoo si bi ijọba awọn wó. O mu ki wọn ṣiṣẹ aṣekara, o si ni ireti pe oun yoo fi wọn ṣe ẹrú nipa nini wọn lara. Ṣugbọn ayanfẹ Ọlọrun ni wọn i ṣe; a si ṣe akiyesi pe ninu gbogbo itan igbesi-aye wọn ni idajọ Ọlọrun n wá nigbakuugba sori awọn orilẹ-ede ti wọn ba ṣe ibi si awọn Ọmọ Israẹli. Awọn ara Egipti yoo jiya nitori pe wọn jẹ oluwa onroro bẹẹ, ti wọn n fi ipa mu awọn Ọmọ Israẹli lati kọ́ ilu, ati lati ṣiṣẹ kikankikan ninu oko, nikẹyin lati ṣe biriki lai fun wọn ni koriko ti wọn yoo fi ṣe e.

Iwe Mimọ́ sọ fun wa pe Ọlọrun gbọ́ gbigbin wọn bi wọn ti n jiya lọwọ awọn akóni-ṣiṣẹ buburu wọnnì, O si rán oludasilẹ kan si wọn. Sibẹsibẹ, wọn ni lati duro fun ọjọ pipẹ ki a to da wọn silẹ patapata

### Àṣẹ Ọba

Ajalu ti o tobi ju lọ ti o wá sori awọn Ọmọ Israẹli ni pipa gbogbo awọn ọmọ-ọwọ ti o jẹ́ ọkunrin. Ro bi inu awọn obi yoo ti bajẹ tó nigba ti awọn ọmọ-ogun yoo wá gbé ọmọkunrin kekere wọn, ti wọn yoo sọ wọn sinu odo! Awọn ara Egipti pinnu lati din awọn Ọmọ Israẹli kù ni ọna bayii.

Nigba ti a bi Mose, iya rẹ ri i pe o jẹ ọmọ kan ti o yatọ, o si pa a mọ fun oṣu mẹta. Boya o fi ẹmi oun tikara rẹ paapaa sinu ewu nipa ṣiṣe bayii, ṣugbọn pẹlu ifẹ obi ti o ni, o daju pe o ni igbagbọ́ ninu Ọlọrun pe ọmọ oun ni iṣẹ kan lati ṣe fun Oluwa, o si yàn lati gbọ́ ti Ọlọrun ju ti ọba lọ.

### Apoti Èèsú

Nigba ti ọmọ-ọwọ yii di ọmọ oṣu mẹta, ko ṣe e fi pamọ mọ́, nitori naa iya rẹ ṣe apoti èèsú kekere kan, o si fi oje igi ṣán an ki omi má ba le wọ inu rẹ. Lẹyin naa, o gbe Mose sinu rẹ, o si gbe apoti naa sori omi. O daju pe o gbadura kikankikan bi o ti fi ọmọ rẹ iyanu kekere yii silẹ, o si fi i rubọ fun Ọlọrun. Oluwa nikan ṣoṣo ni O le ṣe itọju rẹ nisisiyii.

Miriamu, arabinrin Mose, wà ni eti odo yii lati ri ohun ti yoo ṣẹlẹ si apoti kekere yii ti o dá nikan wà nibẹ. Ki ni yoo ṣelẹ bi ọmọ-ogun Egipti kan ba ri i? Ṣugbọn ọwọ Ọlọrun wa lara awọn ti Rẹ̀, O si ṣe eto rẹ to bẹẹ ti ọmọbinrin Farao fi wá pẹlu awọn ọmọbinrin rẹ lati wẹ̀ ni ọgangan ibi ti a gbé apoti kekere ti Mose wà ninu rẹ si. Nigba ti o ri apoti yii, o ran ọmọbinrin rẹ kan lati lọ gbe e wa fun oun; nigba ti o ṣi i, ti o ri Mose ti o n ké, o fẹran rẹ. O mọ pe o jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ti o yẹ ki a pa, ṣugbọn o jẹ ọmọkunrin kekere kan ti o lẹwa to bẹẹ ti o fẹ́ tọju rẹ fun ara rẹ.

Ọmọbinrin Farao fẹ alagbatọ fun ọmọ-ọwọ yii, Miriamu si wà nibẹ lati damọran nipa iya Mose lati ṣe itọju rẹ. Nigba ti a ba fi ohun gbogbo sabẹ itọju Ọlọrun, bawo ni Oun yoo ti ṣe e fun wa lọna iyanu to. Iya Mose ni itẹlọrun lati tọ́ ọmọ rẹ dagba, a si san owo fun un pẹlu.

### Ohun ti Mose Yàn

Lẹyin ti Mose dagba, o lọ gbe ni aafin ọba, nibi ti a ti kọ ọ ni gbogbo ẹ̀kọ́ awọn ara Egipti. Awọn ti n ṣe awari nipa itan aye atijọ ti wa ilẹ jìn, wọn si ti ri ohun ti o da ni loju pupọ nipa ọlaju ti o ga ti o wa ni akoko naa eyi ti Mose jẹ igbadun rẹ. Ṣugbọn awọn ara Egipti n sin oriṣa pupọ; bi o tilẹ jẹ pe a kọ́ Mose nipa ọgbọ́n iyanu ti awọn alufa wọn, o jolootọ si Ọlọrun otitọ, nigba ti o si dagba, o yàn “ati mã bá awọn enia Ọlọrun jiya, jù ati jẹ fãji ẹ̀ṣẹ fun igba diẹ; o kà ẹ̀gan Kristi si ọrọ̀ ti o pọju awọn iṣura Egipti lọ: nitoriti o nwo ère naa” (Heberu 11:25, 26). O kúkú yàn ati gbe igbesi-aye rẹ lati wu Ọlọrun ju lati wu ara rẹ lọ; o si mọ pe ère ti Ọlọrun yoo fi fun oun yoo pọ̀ ju ohunkohun ti ọba le fi fun oun lọ.

### Awọn oluwa Onroro

Ni ọjọ kan, o lọ bẹ awọn ọmọ Heberu wò, o si ri bi wọn ti n ṣiṣẹ lile to.  Aanu ṣe e pe wọn n jiya bẹẹ, o si fẹ ran wọn lọwọ.  Ṣugbọn akoko Ọlọrun kò ti i tó sibẹ, Mose si bọ́ sinu wahala nitori pe o sare ṣaaju Ẹmi Ọlọrun. Oluwa onroro ara Egipti kan n lu ọkan ninu awọn Ọmọ Israẹli, nitori naa Mose gbeja rẹ, o si pa ara Egipti naa.  O da a loju pe kò si ẹni ti o ri oun nigba ti oun n ṣe e, o si bò o mọlẹ ninu iyanrin.

Ṣugbọn ni ọjọ keji, nigba ti o fẹ ṣe ilaja laarin awọn ọmọ Heberu meji ti wọn n jà, ọ̀kan ninu wọn wi pe, “Tali o fi ọ jẹ … onidajọ lori wa?”  Wọn jẹ ki o di mimọ fun Mose pe awọn mọ̀ nipa iwa buburu rẹ ti o hù lana.  Wọn tilẹ lero pe ara Egipti ni oun i ṣe; tabi bi wọn ba mọ̀ pe o jẹ ọkan ninu awọn eniyan ti wọn, wọn le jowu rẹ nitori pe a ti tọ́ ọ dàgbà ni ibi ti o lọla nigba ti awọn ni lati ṣiṣẹ bi ẹrú.  Ohun ti o wu ki o le jẹ wọn kò fẹ ki Mose sọ ohun ti awọṅ yoo ṣe fun wọn.

Ni tootọ ni Ọlọrun ti ṣe eto fun Mose lati gba awọn eniyan Rẹ̀ silẹ sugbọn akoko kò ti i to sibẹ; a si ri pe Mose kò ni ere kan nipa sisare ṣaaju itọni Ọlọrun ati gbigbiyanju lati ṣe iranwọ ninu agbara rẹ̀.  Ki i ṣe igba gbogbo ni Ọlọrun maa n sare ṣe nnkan ni kiakia bi awa ti lero pe Oun yoo ṣe, ṣugbọn ọna Rẹ̀ ga ju ọna ti wa lọ, a si le gbẹkẹle E lati ṣe ohun ti o dara ju lọ fun wa ni akoko ti o yẹ lati ṣe e.

Yatọ si ibinu awọn Ọmọ Israẹli ti Mose mú wá sori ara rẹ, o mọ ibinu Farao, ti o fẹ jẹ ẹ niya; nitori naa o sá lọ si Midiani, nibi ti o wà fun ogoji ọdun.

**AWỌN IBEERE**

1 Ọna wo ni Farao gbà lati din awọn Ọmọ Israẹli kù?

2 Ki ni ohun ti Iwe Heberu sọ nipa Mose ti a fi pamọ fun oṣu mẹta?

3 Ta ni duro ti o si n ṣọna nigba ti a fi Mose sinu apoti kekere naa?

4 Njẹ Ọlọrun ri ẹrù wuwo ti a fi le awọn Ọmọ Israẹli lori?

5 Njẹ Mose yàn lati wà pẹlu awọn eniyan ti rẹ ju ati ni anfaani pupọ ti a fun un ni Egipti?